# EKO AKETE

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"Emi vio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi".—W. T. Stead.

Vol. I. No. 37. SATURDAY, MARCH 24, 1923. Fourpence.



*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,

*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.



N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Meji'la tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A[illegible] orișirisi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni Ọpopo[illegible] ( *Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ o.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun [illegible]uregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ogbẹni S. A. O. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbog yi jẹ ẹniti o gba Așẹ-ogun pipo ( *Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijoba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO. Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọ-ọyọku.

O ti nșowo Irin Ișẹ lorișirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onișowo Irin Ișẹ ni Ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONIȘOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orișirisi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe ( *General Post Office* ) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ ( *Telephone* ) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OȘUNTOLU, onișowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:– Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Așọ oniruru, Itẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, ( *Satin.*)

Ati orișirisi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads (new arrivals from Germany) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AȘỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AȘỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onișowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u pẹlu awọn MAȘINI iranșọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mâse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

### O FOGUN SẸNU B'OYINBO AGBA SỌRỌ? 'WỌ A TUN PỌ O *AGAIN*!!!

Ọdọmọkunrin kan lọsẹ to kọja fi nkan sẹnu ba alagba kan sọrọ: a gbọ pe nigbati o ṣe bẹ tan, o lọ mu epo: warawere, bẹni awọn olóye to wa nibẹ lọ fi ọlọpa-'nu ra "mọ-so-ndoki" yi mu, nwọn si gbe e "niyawo" lọ si ti *St. Anna* (Ṣabu Ọlọpa.)

A gbọ pe Adajọ kekere ti sọfun Dr. Ṣapara ko lọ yẹ ogun na wo: Ọrọ "ọdẹlẹ-sinrin" yi si ti di ti Kotu, bi a ti nwi yi.

### IGIDA!

Anu ṣe ni lati sọ ti ẹwọn oṣu mẹrin pẹlu iṣẹ-aṣegan ti Adajọ Kekere Ọgbẹni M. Green ti Kotu kekere ni Ẹhingbẹti ju Ọgbẹni Samuel Isaacs si, ni *Monday* ọsẹ yi: Ọgbẹni ti a fi sẹwọn yi jẹ ọmọ Alagba Isaacs ti Ọfin, o nṣiṣẹ Aya-aworan nkan (*Draughtsman*) ni Ile-iṣẹ Ọkọ-Ọba (*Marine*) nibi: loju wa, ki-ro ki-fọ ni ọdọmọkunrin yi jẹ: ẹṣẹ ti a fi sun ti o si jẹbi rẹ ni pe o je owo Ẹsu (£128 6/-) ti awọn oniṣẹ-ẹ̀bẹ rẹ, titi kan awọn Irañṣe (*Messengers*) ti nwọn wa nibi iṣẹ kanna da pamọ si lọwọ, ti nwọn si npete ati jumọ pin lakokoọdun Keresimesi to kọja fun inawo ọdun na.

### AIYE-LU-JARA.

Ijọba nṣe ọna kan bọ lati Ipẹru ni Ijẹbu-Rẹmọ titi de Ikẹja ti wa nihin: bẹ si ni a gbọ pe Ode-Ondo koju irin ọjọ meji pere lọ mọ si ilẹ yi, lati Oṣogbo. A ko le ṣẹṣẹ ma sọ tianfani ọpọlọpọ to wa ni ọna-lila bayi fun òwò ati lilọ si ọgọrọ ilu wa loke.

### ILE-IWE GIGA TI EKO ṢE "KISA"

A ba awọn Ọga ati awọn Olukọni ti Ile-iwe (*Eko Boys' High School*) yọ fun ẹbun Ago Fadaka ti "Peter Thomas" ti nwọn jagunmolu gba lọwọ Ile-iwe Giga awọn Aguda (*St. Gregory's Grammar School*) ni Adapọ Ere ti gbogbo Ile-iwe Giga ti *Nigeria* ṣe ni Ọdan ni *Saturday* to kọja: Adele Ọba, Sir Donald Cameron lo pin awọn ẹbun na. Ọwọ a r'oke o!!!

### KIRISI BABA EKO, EBỌRA NILE ẸJỌ.

Ni *Wednesday* ọsẹ to kọja, Dr Ṣapara ṣe iranti ajọdun kẹjọ ti ẹgbọn rẹ Kirisi, Lọya Ọlọla, Oloye C.M.G. ati Oloye odifi ti Idifi, ni Ileṣa, ti pa ipo da: a ṣe Awẹwo diẹ fun awọn ọrẹ ni "Ile Ṣapara" ni No. 41, Opopo-nla fun iranti ọjọ na, ọrun a-gbe ẹ, Ọmọ Ajalọrun.

### LỌYA JIGA NGOKE AGBA.

A ba Ọgbẹni J. Egerton Shyngle yọ fun iranti ọjọ-ibi rẹ ọdun 61—to ṣe ni *Thursday* ọsẹ to lọ.

### ABIAMỌ KUṢẸ!!!

A ba Ọgbẹni Albert Brown ti Ile-òwò awọn Oyinbo Ọlọkọ (*Elder Dempster & Co.*) nilẹ yi kẹdun ọfọ ọmọ rẹ—agbalagba ọmọ ọlọdun 17 to ṣẹlẹ ni alẹ *Saturday* to kọja ni ile baba rẹ ni Ita *Victoria*. Baba ko ṣe e lọmọ ọla.

### E-NMỌ DE! IKU DI MẸFA OKAN!!!

*Motor* pa ọmọdekunrin kan ni apafọn ni gẹrẹgẹrẹ Ẹhin-ọgba ni iwọn agogo mẹrin-abọ ọjọrọ *Thursday* ọsẹ to kọja. Ki nwọn to gbe de ti Dr. Vaughan ni Idunṣagbe, o ti sọ ọrùn nu.

### ẸKU 'RIN, ỌMỌ AJOGB'ẸRU.

A ki Ẹni-ọwọ M. C. Adeyẹmi Oloye B.A. Ọga Ile-iwe Giga ti Ondo fun dide to de ni lọlọyi fun Ere Aṣepọ awọn Ile-iwe giga ti a ṣe ni Ọdan nibi ni *Saturday* to kọja. Ọgbẹni na tun pada lọ sẹnu iṣẹ rẹ ni *Wednesday* ọsẹ yi.

### KI BABA KORE BILISI.

Ina kan ṣẹlẹ ni ile Ọgbẹni J. Mọṣalewa Thomas ni ita Matinin ni alẹ *Monday* ọsẹ yi: a sapa tobẹ ti ko ṣe jamba pupọ. A gbọ pe Oyinbo kan ti Ile-iṣẹ Creighton ni ita Matinin lo tete jẹ ki awọn ara ile ati aladugbo ibẹ mọ pe ina ṣẹlẹ, o si fi mana-mana (*Telephone*) sọrọ si Ita *St. Anna* pe ki awọn ọmọ "Eriwo" mabọ: a si tun gbọ pe iṣe ti Ọgbẹni Olumide Williams ikan ninu awọn aladugbo ibẹ ṣe ki ina na to le ku ki-iṣe diẹ.

---

### TANI MỌ ṢE?

A ba arakunrin wa Ọgbẹni Tunde Abraham ọmọ Ọgbẹni I. E. Abraham, kẹdun iku aya rẹ ni Ita Paṣi to ṣẹṣẹ gbe niyawo ni oṣu to kọja, to ṣẹlẹ ni oru *Wednesday* ọsẹ yi, lẹbin ọmọ-bibi. Ki Baba tu ọkọ yi ninu ati awọn ẹbí rẹ.

---

### SARUMI-ỌWẸ D'ẸNI ỌRUN.

A daro Oloye Iṣẹri Ọdunsi Sarumi to ṣalaisi ni ilu Iṣẹri na ni kutukutu arọ *Saturday* to kọja.

---

## OHUN TI A NI KI ALAJA MA GBỌ ALAJA NI YIO PARI RẸ.

Awọn baba wa ni ima pa owe yi pe "Ohun ti a ni ki alaja ma gbọ ala'ja ni yio pari rẹ," nigbati mo si wadi owe yi, ẹniti o ba sa bere ọrọ, on lo fẹ idi rẹ gbọ, mo si wa ri pe itan kukuru yi lo padi owe na. Itan na lọ bayi pe:—

Awọn ọmọdekunrin meji kan ṣe arinjo lọ si ilu kan, nigbati nwọn de ilu yi nwọn wọ ti ogboni kan ti o ni aja kan. Aja yi tobi pupọ, o si sanra gbẹngbẹ-gbẹngbẹ, ekiki ọra, oju awọn ọmọde wọnyi wọ aja na tobẹ ti nwọn fi ngbero ọna ti nwọn o fi le gba lati fi ṣ'ata. Nwọn ṣọ onilẹ titi, nigbati nwọn si ri pe ko si nile ni ọsan 'jọ kan, nwọn ki aja mọlẹ ka gba'bẹ si lọrun, nwọn si pa opo rẹ nwọn fi gbogbo ifun ati ibi ti o d'ọṣọ gbogbo lara rẹ ṣe imoyo, nwọn wa fi iṣu ka'na lati ba gun 'yan. Iṣu nho lori ina, imoyo si nta firi, awọn mejeji si nsunmu ṣẹnṣẹn, Ọmọdekunrin kini wa ran ekeji lọ si odo lati lọ pọn 'mi wa. Bi eni si ti pẹhinda, ẹlẹgiri tibi wọ'do mọra, o gun'yan bi iyan ti npari, ko kuku ṣe meji, o wa ko ti imoyo eyi[...] a ti nwi yi ti pẹ ati imoyo ati iyan, jagun [...] fi gbogbo rẹ la yanyan, egun ko ku. Bi o [...] kuku ṣe tan, elekeji rẹ de. bi eyini si ti ṣi ikok[...] wo, ikoko ni ki o rọra ṣi on, omitoro ko k[...] bẹni imoyo yi ko kan silẹ, o wa gbija ka bẹ[...] si wipe "Ohun ti a ni ki ala'ja ma gbọ. ala[...] ni yio pari rẹ," ija nṣe ranyin, ariwo nta ge[...] Nibiti nwọn gbe nja ni awọn ara ile gbọ, nwọ[...] si wa lati pari ija na fun wọn, ṣugbọn nigbati wọ[...] ri pe kaka ki awọn le pari ija yi, awọn om[...] mejeji yi ṣa nfọra nwon l'ẹṣẹ nwon si nwip[...] "Ohun ti a ni k'alaja ma gbọ, alaja ni y[...] pari rẹ," nwọn birehin, bi enia ko ba sa le pa[...] ija, ki da kun, nwọn wa kesi balẹ lati wa ṣ[...] atuṣe na, nigbati balẹ de.

Nigbati a ro gbogbo ẹjọ fun u, "Ohun ti a ni k'alaja ma gbọ alaja ni yio pari rẹ" Alaja wa f'ọwọ wọnu, o si bẹ ọtun ati osi, ki nwọn ye pa 'rawọn nigbe. "Ohun ti a ni k'alaja ma gbọ, alaja lo pari rẹ."

FANOKUN,

Ẹnyin agbalagba mo juba nyin o.

---

## ARỌ L'Ẹ WA ṢE TABI ẸWIRI ALAGBẸDẸ L'Ẹ WA WO?

Ẹ ba wa bere boya ao ri ẹnikan ti yio la ewo ni Ọgbẹni Nayyar ba wa ninu awọn nkan mẹrin wọnyi ye wa:—

(i) Awọn ara-ilu oyinbo ni nwọn ran Ọgbẹni Nayyar wa si Eko lati wa wo iru ipo ti Eleko wa ni? Tabi

(ii) Ẹsin *Religion* ni awọn Alawari Ẹgbẹ Ẹsin Madi *Founders of Ahmadia Missionary Movement* ran a wa fun? Tabi

(iii) Nitori ọtẹ Eko ni awọn Alawari Ẹgbẹ-Ẹsin Madi ṣe ran Ọgbẹni Nayyar wa si Eko? Tabi ẹwẹ

(iv) Adabọwọ Ọgbẹni Nayyar ni lati huwa bi ẹniti a ko pe ti o wa bẹ ile wo nipa ọrọ Eleko?

Ko sa tọ ki o yanilẹnu lati ri pe Ọgbẹni Nayyar pẹ larin isọwọ awọn onisọkusọ bi ẹja omi ti ngbe Eko on na papa (Ọgbẹni Nayyar) si huwa gẹgẹ bi ẹrọ-sọrọ-sọrọ *Gramophone* o si nsọ iru ọrọ ti nwọn ma nsọ jade lẹnu ararẹ nitori a gbọ ti awọn alagba powe wipe "Ọrọ ti a ba sọ sinu fere ni fere yio sọ jade."

Ṣugbọn ohun ti o mu [illegible] a, so gbolohun meji yi ni pe ọpọlọpọ awọn oyinbo [illegible] tara ti nwọn ga ju Ọgbẹni Nayyar lọ bi ẹgbawa ti ga ju okan lọ, ti nwọn ni ipin ninu ọrọ Eleko gẹgẹ bi iṣẹ nwọn, ti nwọn riran ati, ti awọn ti ni ọla ni Eko ju Ọgbẹni Nayyar yi lọ ti wa ni ilẹ yi fun ọdun gbọrọ ti nwọn ti nlọ si ile wọn ti nwọn si ti npada bọ si Eko nigba pupọ ṣugbọn a ko ri ki ẹnikan ninu wọn sọ isokuso si Eleko lara bayi ri. Bẹni ohun ti o mu ki Ọgbẹni Nayyar mọ wahala ọpọlọ-agbari rẹ lori ọrọ Eleko ko ye ni si. Bi o ti lẹ ṣe pe a mu Ọgbẹni yi ni mọwọ-mọrun pe ki o wa rohin ohun ti o ri ni Eko, njẹ ọgọro nkan miran ti o lẹ rohin ko si?

Boya, ẹwẹ, nitori ti Ọgbẹni yi ki yio pada wa si Eko mọ gẹgẹbi a ti ngbọ irohin lẹnu ninu awọn Ọmọ-Ẹgbẹ-Ẹsin rẹ ni o mu ki Ọgbẹni Nayyar huwa gẹgẹ bi owe ti awọn alagba npa wipe "Bi Oyinbo ba fẹ lati lọ kuro ninu ilu yio ṣu sori aga," a ko mọ. Ṣugbọn ẹ jẹ ki a ranti pe bi enia ba jẹ enia kukuru niya, Ọlọrun yio mu enia gungun wa lati san a fun u.

EFIN-N'-IWA.

---

To the Editor "Eko Akete".

A Sacred Cantata entitled THE SEVEN LAST WORDS ON THE CROSS will D.V. be rendered by African Bethel Church Choir on Good-Friday March 30, 1923 at 7.30 p.m.

Characters of the Cantata will be illustrated by exhibition of Magic-Lantern and address.

Words of the Cantata will be sold at the Church gate at 3d. a copy.

Collections will be taken.

OTHNIEL TAYLOR,

*March, 1923.* *Organist & Choirmaster.*

---

### A MUSICAL TREAT.

We are asked to announce that the rendering of an Oratorio by the Christ Church Pro-Cathedral Choir entitled "The Passion of Christ" by Dr. Somervell (1st time of Performance) will (D.V.) take place on the evening of Good Friday at 7 o'clock.

The work is in the seven scenes beginning with "The Last Supper" and ending with "The Seven Last Words" on the Cross.

It is profusely interspersed with hymns with popular tunes in which the congregation may join and is of a highly devotional character.

The pamphlets of words are on sale at 3d. a copy at C.M.S. Bookshop, Lagos.

---

## ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Ni ipade ajọdun kẹsan Idapọ Ijọ Ọmọ Ibilẹ *African Communion* ti wọn ṣe ni oṣu *August* 1922 ti o kọja ni wọn tẹwọgba aṣa lati ma 'kọrin ni ohun ilẹ wa pẹlu Batakoto ati ohun elo miran. Lati igbana wa ni orişiriṣi ijọ ti o faramọ *African Communion* ti ngbiyanju lati mu ki orin kikọ ni ohun ilẹ wa di ohun aigbọdọ maṣe, papa l' akoko isin akanse, tobẹ ti a fẹrẹ sọ aṣa na di ọpọku.

Ọpọlọpọ ninu awọn Ijọ ọmọ Ibilẹ ni o ngbero pẹlu mi bi a o ti ṣe le mu aidọgbayi kuro; gẹgẹ bẹni ẹgbẹ kan ti a npe ni Idapọ ẹgbẹ akọrin ijọ ọmọ-ibilẹ *African Church Choir Union* ni ipade kan ti wọn ṣe ni lọloyi, wọn sorikodo lati jiroro nipa bi idọgba yio ti ṣe wa ninu kikọ orin ni ohun ilẹ wa, ọkan ninu imọran wọn ni pe awọn yio kọ iwe si awọn Ojiṣẹ-Ọlọrun ti o wa ninu Ijọ-ọmọ Ibilẹ fun iranlọwọ ati atunṣe ninu kikọ orin ni ohun ilẹ wa. Bi ẹda iwe na ba tẹ mi l' ọwọ, mo ni ireti wipe yio jade ninu iwe irohin yi ni igbamiran.

Nko le ṣe alaidẹnu le ipade ariyan-jiyan *Debate* ti wọn ṣe ninu ile ẹkọ giga *Grammar school*, nibiti wọn daba pe o to akoko lati ma kọ awọn ọmọ ile ẹkọ ni orin ni ohun ilẹ wa; o ta si ni leti wipe Ọgbẹni T. K. E. Phillips ṣe ariyan-jiyan wipe a ko ni orin ni ohun ilẹ wa gẹgẹ bi enia dudu; bi o ba jẹ wipe nitotọ li o wi bẹ, yio yani lẹnu gidigidi lati gbọ irn ede bẹ lati ẹnu Ọgbẹni na wa, nigbati a ba ranti orin aro *Native Dirge* ti awọn ẹgbẹ akorin kọ ni *Church Breadfruit* ni Isin iranti Ologbe *Bishop* Johnson ni Ọdun 1917, eyiti o jẹ pe ọgbẹni na ni o ṣe e *(compose.)*

Eyi t' oku di ọjọ miran

OYENẸYE

# EKO AKETE:

EKO, SATURDAY, MARCH 24, 1923.

## KO TẸ KO TẸ, KONGRES KO TẸ MỌ OJU T' ẸLẸGAN O!

Ojulowo ọrọ ni a ri ka ninu Iwe-irohin orimayaki ti a npe ni *Gold Coast Leader* ti awọn ara wa ni Ilu Aganyin, ati eyi ti a tun ri ka ninu Iwe-irohin ti Ilu Saro ti o njẹ *Sierra Leone Weekly News*, nipa ti lilori ti Apejọpọ Ekeji ti awa ọmọ *Africa* lọ ṣe ni Saro lori, ni oṣu *January* to kọja: irohin yi jẹ iṣiri nlanla fun gbogbo wa nitotọ pe Ina Ọlọrun ntan, ati pe lai f' ọta pe, Iṣe Irẹpọ wa gẹgẹbi ọmọ-iya lati Ilu Gambe titi de *Nigeria* nlọ siwaju ati siwaju

Nigbati a da Ipade yi silẹ ninu oṣu *March* ọdun 1920, ko si bi awọn olori-buruku to wa larin wa nibi ko ti ṣe to, pe ki nkan na maṣe lori, nitoripe nwọn ro pe ohun-kohun ti nwọn ko ba lọwọ si di nkan lasan, ṣugbọn irufẹ awọn bẹ gbagbe pe "Koriko to ni ki Erin ma goke alọ, yio di a-lọmọlẹ lẹsẹ Erin:" bi iru awọn ẹni bayi ko ba si laiye, Iṣẹ Odumare yio ma lọ bakanna, ti ko pada; tani njẹun, t' aja nju 'ru?

Fun gbogbo ọjọ ti a ṣe Ipade yi, ni ibi ti a wi yi, a gbọ pe yungbayungba bi agbayun ni gbogbo rẹ ndun. Ẹni-ọwọ J.C. O. During, Oloye M.A., Ogunna-gbongbo ninu Iwe, lo kọ ṣi Ipade na nipa Iwasu gbigbona to ṣe ni Ile-Isin ti a npe ni *Wesleyan Church* ni ọjọ 23 oṣu *January* Iwe to fi wasu ni Iṣe Awọn Apostili Ori 25 Ẹsẹ 11 to sọ bayi "Mo fi ọran mi lọ Kesari," ninu awọn Ọgbẹni to sọrọ ni Ajọ na ni Casely Hayford Ọlọla. Atari-Ajanaku -ninu-iṣẹ rere fun ilu, ẹniti o jẹ igbakeji Baba Ẹgbẹ Kongres na, Ọgbẹni C. May Ọlọla, Oniwe-Irohin ti a npe ni *Sierra Leone Weekly News* gbẹn-ngbẹn-nenkẹn, awuwo-bi-atẹ-ibanujẹ: Bankọle Bright Onisegun Ajidewe, Ọgbẹni A Nelson Loya-amu-bi abẹ-ẹtẹ. Iya-afin Nora Taylor Ṣingi-nibi, bi o ṣeṣọ ti ọdọ awọn ara wa wa lati Ilu *America*, Ọgbẹni Samuel Richard Wood Akuru-yẹjọ, ti o ṣ Sẹkiteri gbogbo Agbajọ Ẹgbẹ na, ati awọn jakanjakan miran.

Gomina ibẹ, A. R. Slater Ọlọla ati Oloye C.M.G. si gba awọn enia wa na towọ-tesẹ nigbati nwọn lọ kansẹ lọdọ rẹ, kete ti Ajọ na bẹrẹ: bayi ni awọn enia wa ṣiṣe ribiribi ninu Ipade keji yi, awọn ikọ ti Ilu Aganyin si pada wa 'le ni ọjọ 19 oṣu to kọja.

Bi o tilẹjẹpe a kole rau enia lọ nibi bi ti ọdun 1920, nitori aiya ilu ti ko ti balẹ nisisiyi, sibẹ ina ẹgbẹ yi koku larin wa, nitori laipẹ yi ni diẹ ninu awọn agba Ẹka ẹgbẹ na nibi awọn bi Dr. Akinwande Savage, Ọṣọ Davies Ọmọ-Ọba, Ọgbẹni Cardoso ati awọn miran pe apẹja fun meji ninu awọn oloye Ẹka-ẹgbẹ na ti ilu Calabar, ni ileonjẹ ti a npe ni *Grand Hotel* lọdọ wa nibi nigbati nwọn wa bẹ ilẹ yi wo.

Njẹ a ko le ṣai dupẹ lọwọ Baba-ọrun pe, ninu gbogbo ofi-ọla ti Eko wa isisiyi, Ẹgbẹ yi si nmi titi di oni, a yin Oluwa!!!

Ko tẹ ko tẹ, Alàrà ko tẹ ko tẹ,
Kongres ko tẹ mọ oju t'ẹlẹgan o,
Oju t'eke o, Yegẹdẹ! oju ti wọn. o
Yègẹ̀dẹ̀!!!

---

CHANGE OF NAME.

I Michael Adol Martins formerly known and addressed as above, beg to inform the public a general that from and after 1st day of April, 1923, all letters documents, should be addressed to me as ADEYẸMI OṢONARIWO.

Any letters or documents, bearing the former name before this date remain valid ADEYẸMI OṢONARIWO.

# SINGER! SINGER!! SINGER!!!



Kinla! Tiwa ki nse a nṣẹṣẹ wa onibara, kini a ti nṣ'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọbu larin orişirişi enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranṣọ "SINGER" kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu 'Ẹlẹha jade ọsan' ni iwipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogunlọgọ onibara wa

TI EDINWO NLNLA TI A ṢE

ninu owo ẸRỌ IRANṢỌ wa ati IRIN-IṢẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

wọnyi ni diẹ ninu awọn ohun pataki ti o jẹ ki ẸRỌ IRANṢỌ SINGER t'idi awọn ẹrọ iranṣọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu iṣẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri orişirişi irin iṣẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Ikẹta.—Ifọwọsọ'ya lati tun gbogbo Ẹrọ Iranṣọ 'SINGER' ṣe nigbakugba l'ọfẹ ibaṣepẹ a ra lọdọ wa tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Popo nla l'eko nibiti 'Ẹrọ Oyibiri' nl'agogo.

Phone L222, Extensions 2 & 3.

P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,

*Sole Importers Singer Sewing Machines.*

---

# ILE EGBOGI TITUN.

Fun irọrun ati anfani gbogbo awọn ti ngbe Olowogbowo, Ita Balogun, Oke-arin Ọfin, Idumata titi lọ de Victoria Road, a ṣi Ṣọbu Egbogi titun kan ni Ita Balogun.

*No. 69, Balogun Street,*

Ṣọbu yi jẹ ọka Ṣọbu nla ti Filipi ni Ajẹlẹ ati Ita Faji—

*Phillips Medicine Store.*

Egbogi ojulowo pọ nibẹ. Ma fi ọpọ silẹ nitosi lọ ra ọwọn ni ọna jijin.

## ỌRỌ TO KA 'YIN.

Irohin ti a ngbọ lati' ẹnu oṣu meloyi pe a o pa igbimọ lailai ti a ti nṣe ti, a o si ma ṣe titun ni gbogbo *Nigeria* ilẹ enia dudu niha ti wa nihin, ninu eyiti Eko ilu wa yi jẹ ọkan pataki ninu rẹ; ati pe wọn nfẹ enia mẹta pataki, ọlọgbọn, oloye ati ololọ ti ki yo fi dudu pe pupa tabi pupa pe dudu fun wa, nipa wiwa ọla tabi ogo ara wọn nikan, ti wọn yio ma ṣe iriju na fun idagba soke ilu wa yi gẹgẹ bi ijọba Gẹsi *British Government* ti nfẹ rere fun wa bi ọmọ.

Ati pe lati ma ri awọn Ijoye, Ọba ati awọn agba ilu tòtò ki nwọn to lọ tabi bi nwọn ba bọ fun awiye ọrọ, gẹgẹ bi nwọn ti nṣe nibi gbogbo agbaiye, ki ijiyan tabi ede ko-ye-de le tan larin wa, bi ti atẹhin wa ọrọ diẹ to fun ọlọgbọn.

ỌMỌ EKO.

## EYI MA SU NI, O KA NI LAIYA O, HỌWU.'

Awọn agba a ma sọ pe "bi o lu ọrọ, nwọn a ni o lu ọrọ, bi ọrọ si lu ọ, (iwọ kọ o, owe lo lọ bẹ o!) nwọn a ni ọrọ lu ọ," ewo la ha ṣe bayi o? mo ro pe, owe lailai ni, a fẹrẹ le ma pa owe na ni sa tiwa bayi pe "bi o lu ofin, nwọn a ni o lu ofin, bi ofin si lu ọ, nwọn a ni ofin lu ọ."! Ọrọ lu ni ni o, ofin lu ni ni o, ewo lo ṣanfani? ki Ọlọrun ma jẹki ofin lu wa, ki a ma si lu ofin o. Ẹ ko wa ri pe ofin ko mọ ẹnikẹni? ati talaka ati ọlowo, apẹpọ. Nitorina, mẹlọmẹlọ ni ẹ jẹki a ma lọ o, ki a ma pẹ ofin, ki maṣe jọ rin lọna kan na.

Awọn opintan, nigbati nwọn nsọrọ idajọ ododo, nwọn ni ngbati awọn ara *Egypt* nyan aworan ofin, nwọn gbe e kalẹ o joko pinrin, ṣugbọn ko ni oju, ko si ni ọwọ! Ẹnikan si bere pe, họwu, eṣe ti ko fi ni oju ati ti ko si ni ọwọ? ọlọgbọn kan wa dahun pe, ko ni oju ki o ma ba ṣanu fun ẹnikẹni, ko si ni ọwọ ki o ba gba abẹtẹlẹ! Kai! o ko ri ọgbọn bayi? nijọ ti ofin ba loju, yio ma riran lati ṣanu ọlọmọ kan, opo, talaka, bi nwọn tilẹ lu u bayi, nijọ ti ofin ba ni ọwọ, awọn olowo yio lu u bolẹ bayi, nwọn a si fi owo pa a lẹnu mọ tobẹ ki o le ta bntu. Kini owo pa ti ko ku o? Ẹnu ofin gbo ke ke, a ma ke pe, o lu mi o, ng o si lu ọ san. O maṣe o! wo awọn ti ọlọpa nko bọwa Kotu Ọba yi o, nwọn lu ofin ni, awọn bi ole, abaniloruko jẹ, ọmọ ita, alafọwọra. ọlọṣa ati bẹ bẹ lọ, nigbati ofin ba si fẹ gbẹsan ti yio ba lu wọn, o di inu ẹwọn airotẹlẹ. Ki Edumare gba ni lọwọ agbako Eṣu o. Sa ma lọ mẹlọmẹlọ, afọju to riran loru ni ofin, ofin alailọwọ, a fi ẹṣẹ ku bi ojo. Maṣe lu ofin o, jọwọ ma jẹki ofin ṣiwọ lu ọ rara. Ẹ ko gbọ iyẹn nọ?

**OLD GRAMMARIANS' SOCIETY**

ANNUAL MEETING.

General Meeting will D.V. take place at the Great Hall of the C.M.S. Grammar School on Friday, April 6th at 5.30 p.m.

G. D. AGBEBI,
*General Secretary.*

**FIRST CLASS TONSORIAL ARTIST.**

Mr. A. L. KOSỌKỌ the well-known Barber late of Customs Street, Lagos; begs leave to inform his many clients of his new Establishment at 135, Victoria Road, this City, where prompt attendance will be accorded them as heretofore.

Razors, Combs, Perfumes, etc, are also on sale at prices to suit everybody.

Call or send; warm wellcome to all.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si lẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa oriṣiriṣi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

**DRESS-MAKING.**

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ o.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kõtu, l' Eko.

---

## WANTED.

Reliable Agents required for sale of English Ready-made COFFINS, at Lagos Abẹokuta, Ibadan and Jẹbu-Ode.

For Terms and Conditions,

Apply to A. BANK. ANTHONY, 137, Tokunbọ Street, Lagos.

---

## A TOTO, O!

A nfẹ Enia "GIRIKI" ti yio ṣe oju Ọgbẹni A. BANK ANTHONY ni Eko, Abẹokuta, Ibadan, tabi Jẹbu-Ode, lati ma a ta awọn POSI-meremere, ti o ti ilu Ọba wa fun Ọgbẹni Onisowo na.

Ẹniti o ba nfẹ, ki o kọwe si Ọgbẹni na. ni adugbo rẹ 137 Ita Tokunbọ l'Eko.

---

## "O ṢE' WỌ NI!" ( FAIR WARNING )

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

### EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ọwọ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsọ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,)

Jurgens Colonial,

Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)

MacIver, African Products,

Association, John Holt, Miller Bros.

Paterson Zochonis,

£14 10 de £15 fun *ton* kan

### EPO.

£24 10 de £25 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

### COCOA.

Lati £27 de £28 fun *ton* kan bakanna ati Agege £28 0 0.

---

## The Philharmonic Band.



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY*,

c/o Anfani Motors

The Marina Lagos.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

( MORNING )

Masses Isin Aro.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)

Masses /Benediction ) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's ( Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m., 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon. T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's ( Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity ( Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J A Leigh |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | | do. do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. J. C. Cole |
| 7 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. D. A. Beckley |
| 7 p.m. | | do. |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | | Rev. G. A. Oke |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. T. A. White |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. J. A. Wright |
| 6.30 p.m. | | Bro. E. A. Fayan |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. A. T. Iroko |
| 4 p.m. | | Rev. I. O. Oyekunle |
| 9 a.m. | Ararọmi ( Baptist) | Bro. J. J. Tubi |
| 4 p.m. | | Bro. John Apena |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. A. Oṣodi |
| 6.30 p.m. | Bro. J. Adekọya |

**BROTHERHOOD**

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Pastor A. Adedeji Iṣọla |
| 7 p.m. | | do. |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Bro. Thomas Akajagbo

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe ( Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon
Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

---


SIMENTI NYAJU!!!

Ọgbẹni Mumuni Ainde ti No. 27, Ita Masse L' Eko ni ojulowo *BIRIKI* fun tita fun ẹnikẹni owo wọn si rọju.

Ẹnikẹni to ba nfẹ ba Ọgbẹni na ra awọn *BIRIKI* yi le lọ ke si i ni adugbo rẹ.

Ki a ri nyin o, Ẹnikeji, Ijafara lewu.

---

W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L'ỌRỌ WÀ!!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ati ni Ṣabu ALAJI MASU ni Ila Agarawu ni owo ọpọku-ọyọku.

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER, Oniṣowo ara Jamani ni Ita 7, Labinjọ, leti Ita William lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin, ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE
Awo Abọmafa ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.
Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

## Mo gbe tana danu Mo gbe miran de.

Ile Egbogi ti a npe ni Işẹ Olodumare ti o wa ni ... Iga Oloye Aromirẹ ni Ọbun Eko, kun fun orişirişi awọn Egbogi wonyi ti o şẹşẹ de :—

Egbogi Kurunn, ati Ọşẹ rẹ, Egbogi Işaka, Ijedijedi, Ela ọmọde, Iba, Ipa ọrẹrẹ ọmọde, Egbogi Ẹda ati Aran Kinişa, Egbogi Inu riru ..., ati fun ọkonrin pẹlu, egbogi ki ara ọkun- ... le giri (ko ma ye ẹ) ati orişirişi awọn eyiti a ko le daruko tan.

Sẹ lọ sibẹ, ki olora tirẹ, ọpọkuọyọku ni, bi o fẹ lori, oma dowọ rẹ o,

"Arun ma jogun, udagba si ẹlẹda rẹ.".

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

1?8 Great Bridge Street,
Ita Onilọvi, Idunmota,
Lagos.

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aşoju wa,

Ajeniiuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

---

WHY LOOKING SAD ?

Are you impotent, suffering from sexual weakness, nervous postration or loss of memory why don't you use Muiracithin and get instant relief. It will rejuvenate you, and restore your youthful energy. Its effect is wonderful and permanent. No matter how Chronic your case may be. It is also unsurpassed remedy for women in case of barreness, irregular Menstruation sexual Neurasthenia etc, etc. In order that every sufferer should have a trial of this valuable Medicine, the prices are reduced for only limited time at 4/6 in bottle of 50 pills and 6/6 in bottle of 100 pills obtainable at "Ajeniiuja" Store No. 109 & 111, Broad Street

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

---

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onişowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

Ni wa iwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ... tita: Şẹrẹkẹ şin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

E tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ni lọ.

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jarẹ ẹ sọ pe ninu Iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

First Class Dressmaking!!!

Mrs. ABRAHAM ASHARE trained in Paris, begs to offer her professional services to the public.

Latest modes at moderate charges satisfaction gauranteed. Call at once at

117, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

---

PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

! Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-m'ẹşọ ti o si nta ni ita oloko o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile ọja na, ti a nşe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi şile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi orişi-rişi iwosan onirunru aisan, Ipara olo-orun, ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin işẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku yọku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati şi ile Ẹrọ Idan Awoşẹju ti a npe ni (*Cinema*) ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Şoroko a gbe şeranwo ni igbati o ba şi ibẹ
Irohin ko to afojuba.

*P.O.Box 159* *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ

108, Moloney Bridge St,

P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.

*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

---

20, Oripasan Lane,
King's Quarter, Isale Eko,
Lagos, Nigeria.

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experience in Dirty Window Cleaning & hanging of Plain Window to any colour or kind of Pattern in Flowers cleaning or white washing of wall to any kind as Distemper colour etc. Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Vanish and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint House and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogali,**
*General Manager.*

---

Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o si ... Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ... J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina ... Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ ...

Lati *Monday* de *Saturday.*

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo.

Ogun rẹ jire.

---

GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.

8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti ng' oku l' ọrun?

Ki la ti ng' ori nile Iku?

Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni—

8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.